# AWỌN ASỌTẸLẸ NIPA MESSIA

## LATI INU PSALMU

**Orin Dafidi 2:1-12; 22:1, 18; 45:1-17; 68:16-19; 69:21;**

**110:1-7; 118:21-24; 132:11**

**ẸKỌ 470 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ" (Orin Dafidi 2:7).**

**I Bibọ̀ Messia,Iwa-Ọlọrun, ati Jijọba Rẹ̀ lori Gbogbo Ayé**

1 Awọn ọmọ-alade ayé ditẹ̀ pọ̀ si Ẹni-ororo Oluwa, Orin Dafidi 2:1-3; Iṣe Awọn Apọsteli 4:25-27; 1 Samuẹli 16:13; Matteu 3:16, 17
2 Oluwa yoo ti ipasẹ Ẹni-ororo Rẹ̀ bi awọn ọlọtẹ̀ ṣubu, Orin Dafidi 2:4-6; 37:12, 13; 59:8; Owe 1:26; Orin Dafidi 132:11
3 A fi ipo Ẹni-ororo naa hàn, Orin Dafidi 2:7-9; 68:16-19; Heberu 1:5; 5:5; Kolosse 1:16, 17; Ifihan 2:27; 12:5; 19:15
4 Ikilọ ti o lẹru ni a fun awọn ijoye ati eniyan, Orin Dafidi 2:10-12;89:7; 35:10; 34:8; 40:4

**II Asọtẹlẹ Iyà Kristi**

1 Kristi jiya lori agbelebu, Orin Dafidi 22:1;69:21; Matteu 27: 46, 34, 48; Marku 15:34, 36; Isaiah 53:4, 5
2 A pín aṣọ Rẹ̀, Orin Dafidi 22:18; Johannu 19:23, 24

**III Igbeyawo Ọba ati ti Ọlọla Iyawo Rẹ̀**

1 A ṣe apejuwe ẹwa Ọba ati Ogo Rẹ̀, Orin Dafidi 45:1-8; Owe 8:6-9; Orin Sọlomọni 5:10-16; Luku 4:22; Isaiah 63:1-6; Heberu 1:8, 9; Efesu 5:23-25
2 Iyawo ati awọn ẹgbẹ́ rẹ̀ ni a ṣe lọṣọ fun Ọkọ, Orin Dafidi 45:9-15;Orin Sọlomọni 1:3, 4; 2 Kọrinti 11:2; Matteu 22:11, 12; Isaiah 35:10; Ifihan 19:7; 21:9
3 Ọba n ṣe rere, Orin Dafidi 45:16, 17;Isaiah 53:10, 11; 61:9

**IV Ijọba, Oye-Alufaa ati Iṣẹgun ti Messia**

1 Awọn ọta Kristi ni a o bì ṣubu, Orin Dafidi 110:1-3;Matteu 22:41-45; 28:18-20; Orin Dafidi 96:9
2 Oun yoo jẹ́ Alufaa, yoo si bori ohun gbogbo, Orin Dafidi 110:4-7; Gẹnẹsisi 14:18; Heberu 5:6; 6:20; 7:1-10, 17-21; Orin Dafidi 21:8, 9; Ifihan 6:15-17; Isaiah 11:3, 4; Orin Dafidi 27:6
3 Jesu Kristi ni Pataki Okuta Igun-ile, Orin Dafidi 118:21-24; Matteu 21:42; Iṣe Awọn Apọsteli 4:11; 1 Peteru 2:4, 7

## ALAYE

Psalmu keji jẹ́ nipa Messia o si tun jẹ́ asọtẹlẹ. Ọpọlọpọ Psalmu ti a ti kọ niwọn ẹgbẹrun ọdun ki Kristi to de ni o ni asọtẹlẹ ninu wọn ti ko le tọka si ẹlomiran bi ko ṣe Kristi. Bi o tilẹ ṣe pe awọn ọrọ psalmu miiran n tọka si Dafidi Ọba, idile rẹ̀ ati ijọba rẹ̀, o hàn gbangba pe Kristi nikan ṣoṣo ni o le mu ileri Ọlọrun ṣẹ fun Dafidi ni ti Itẹ́ Ayeraye (Wo 2 Samuẹli 7).

### Awọn Keferi ti n Binu

Ibinu awọn Keferi n tọka si iditẹ̀ awọn Ju ati Keferi si Kristi. O ni imuṣẹ lapa kan ninu wiwá Kristi ni igba kin-in-ni (Iṣe Awọn Apọsteli 4:25). Iyoku asọtẹlẹ naa ni a o muṣẹ ni akoko wiwá Rẹ̀ lẹẹkeji nigba ti awọn ọba ayé yoo gbá ara wọn jọ si Jehofa ati Kristi Rẹ̀ ni abẹ́ Aṣodisi-kristi. Idajọ Ọlọrun yoo wá sori imọ ati iditẹ̀ wọn si Ọlọrun ati Ọmọ Rẹ̀. "Ẹniti o joko li ọrun yio rẹrin: Oluwa yio yọ ṣùti si wọn." A! ẹru nla nigba ti Oluwa ba n yọ ṣùti si awọn eniyan ti o bá si n rẹrin idaamu wọn nitori "ẹnyin ti ṣá gbogbo igbimọ mi tì, ẹnyin kò si fẹ ibawi mi" (Owe 1:25, 26). Eniyan tabi eṣu kò le yi ipinnu Ọlọrun pada lati fi idi Ọmọ Rẹ̀ kalẹ bi Ọba ninu ayé ni Jerusalẹmu.

**Kristi Jẹ́ Ọmọ**

Onipsalmu fi hàn pe Ọmọ ni Kristi I ṣe: "Iwọ li Ọmọ mi," ki i ṣe nipa agbatọ bi kò ṣe nipa jijẹ "Ọmọ bibi kanṣoṣo lati ọdọ Baba." Ijọba Kristi yoo ká orilẹ-ède awọn Keferi ati abọrişa ati gbogbo awọn wọnni ti ko i ti tuuba fun Kristi. Iṣakoso Rẹ pẹlu ọpa irin ati idajọ ododo yoo bori idojukọ gbogbo. A kilọ fun awọn ọba ati awọn onidajọ lati mura silẹ de bibọ Ijọba yii. Njẹ, jẹ́ ọlọgbọn nisisiyii, fi ibẹru sin Oluwa. Maa yọ ninu ijọsin pẹlu itẹriba tabi ki o jiya ère ibinu Rẹ lori awọn ti o dojukọ Ihinrere Oluwa wa Jesu Kristi (2 Tẹssalonika 1:8). A fi ibukun sori gbogbo awọn ti wọn gbẹkẹ wọn le E. Igbẹkẹle ti a sọrọ rẹ nihin ni a n lò ninu Majẹmu Laelae fun igbagbọ́ si igbala ninu Ọlọrun. Ṣe akiyesi pe ẹsẹ mẹta ti o kẹyin Psalmu naa jẹ́ idahun si ẹsẹ mẹta ti o ṣiwaju rẹ. Idahun si iṣọtẹ si Ẹni-ororo Oluwa wà ninu imọran ti a fi fun ni lati fi ẹnu ko Ọmọ naa lẹnu ati lati sin Oluwa.

**Ijiya Kristi**

Bi a ti n ka Orin Dafidi ori kejilelogun ẹsẹ kin-in-ni, oye yé wa ni ti pipé ti o wà ninu imisi atọrunwa ti ó wà ninu Iwe Mimọ. Wọnyii gan an ni ọrọ Kristi lori agbelebu. Awọn ọrọ asọtẹlẹ nipa wiwa saye Kristi lẹẹkinni ni a muṣẹ bẹẹ gẹgẹ to bẹẹ ti o fi n fi igbagbọ sinu ọkàn awọn Onigbagbọ́ lati mọ pe a o mu awọn asọtẹlẹ nipa bibọ̀ Rẹ lẹẹkeji ṣẹ kinni-kinni pẹlu. Ọrọ lati inu Psalmu yii nipa ti Agbelebu n sọ ti irora ọkàn Kristi ti o jinlẹ jù lọ ninu irubọ arọpo Rẹ. Wọn si tun n tọka si otitọ aileyipada yii pe Ọlọrun ko le wo ẹ̀ṣẹ, ani nigba ti a mu Kristi paapaa, "Ọmọ bibi kanṣoṣo" lati fi "ṣe ẹ̀ṣẹ fun wa." Ọlọrun dá agbara Rẹ duro lati dá Kristi silẹ kuro lori agbelebu ki a ba le mu eto mimọ́ Rẹ fun igbala ṣẹ. Ninu eto Ọlọrun, Ọdọ-Agutan Rẹ ni "a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye" (Ifihan 13:8). Tifẹtifẹ ni Kristi fi bọ́ si àye Rẹ ninu eto Ọlọrun. O le yẹ irora yii silẹ, ṣugbọn adura Rẹ duro bayii pe, "Ṣugbọn ifẹ ti emi kọ́, bikoṣe tirẹ ni ki a ṣe" (Luku 22:42). Imuṣẹ Orin Dafidi 22:18 ni a fara balẹ kọ silẹ ninu Johannu 19:23, 24. Orin Dafidi 69:21 ni a ri imuṣẹ rẹ ninu Matteu 27:34, 48.

**Orin ti Messia**

Ọkàn ti o kún akun-wọ-silẹ ti o si n hó fun ayọ̀ ni a fi bẹrẹ Orin Dafidi 45. Onipsalmu n gbé Ọba ga fun ẹwa Rẹ, oore-ọfẹ Rẹ, ati iṣẹgun Rẹ. Lati ọdọ Ọba ninu ogun, Onipsalmu yipada sọdọ Ọba ninu alaafia. Ododo ijọba Rẹ ni a fi ọpa-alade otitọ ṣe apejuwe rẹ. Ijọba ainipẹkun Messia naa ni a sọ pe, "Lai ati lailai ni itẹ́ rẹ." Pipe ijọba naa ni a fi hàn nipa "Iwọ fẹ ododo, iwọ korira iwa buburu." Eyi jẹ́ idaniloju pe ijiya jẹ́ ere ẹ̀ṣẹ ati pe a o si san ere fun igbọran. Ni titọkasi "Ọlọrun, Ọlọrun rẹ" o n fi iyatọ saarin Ọba yii ati Ọlọrun funra Rẹ. Ororo ayọ jẹ ami lati fi inudidun hàn ati ere fun iṣakoso ododo. A yin Ọba naa gẹgẹ bi eniyan, jagunjagun ati alakoso.

**Igbeyawo Ọlọla**

Nisisiyii a n sọrọ Rẹ bi Ọkọ Iyawo. Aṣọ Rẹ ni a sọ pe o kun fun awọn ikunra oloorun didun ti Ila-Oorun eyi ti wọn i maa lò ni akoko ariya. Nigba pupọ ni wọn i maa fi ehin erin tẹ́ inu aafin, wọn a si ni ọṣọ ehin-erin ninu. Ọlanla awọn iranṣẹ nibi aṣeyẹ yii ni a fi awọn ọmọbinrin ọba ṣapejuwe. Ni ọwọ ọtun ni ayaba, tabi Iyawo Ọba gbé duro ni àyè ẹyẹ ati alajọpin ninu agbara. Ọṣọ rẹ ni wura Ofiri, eyi ti a mọ̀ ni pipé ju lọ ni igba naa; tabi, ni ọna ti Ẹmi, ọṣọ mimọ́ ju lọ ti eniyan le ri gbà, "aṣọ ọgbọ wiwẹ ti o funfun gbõ" (Ifihan 19:7-9), eyi ti i ṣe ododo awọn eniyan mimọ́. Imọran lati dẹti silẹ tabi lati fara balẹ gbọ́, ti a fun ni nihin wà bakan naa gan an lonii fun awọn ti a pè si Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. "Gbagbe awọn enia rẹ, ati ile baba rẹ." Ijọ Kristi, tabi awọn "ti a ti pe jade" kuro ninu ayé, ni a fi imọran fun lati kọ ará, ẹbi, ani ohun gbogbo silẹ nitori Kristi. Ọba n fẹ ẹwa ti Ẹmi ninu Iyawo Rẹ; oun (iyawo) naa si n sin In. Iwa mimọ́ ati ẹwa rẹ, ati ti awọn iranṣẹ rẹ yoo mu inu Ọba dùn. Psalmu yii pari pẹlu ọrọ yii pe orukọ Ọba naa yoo wà ni iranti ni iran gbogbo.

**Ijọba Rẹ**

Ninu Orin Dafidi 110, awọn ọrọ ti o ṣiwaju n sọ nipa ohun ti Oluwa sọ fun Messia. Eyi jẹ bi a ti i kede ọrọ ijinlẹ, "Jehofa wi pe" tabi "bayi li Oluwa wi." Oluwa Dafidi, tabi Kristi ni a si n sọ nipa Rẹ. Aṣẹ lati "joko li ọwọ ọtún mi" n tọkasi aṣẹ ati ipo agbara ti a yà sọtọ fun Kristi. Bẹrẹ lati igba ti Satani ti gbiyanju lati já agbara gbà ni Ọrun titi a fi sọ ọ́ sinu adagun iná (Ifihan 20:10), o ti n gbiyanju lati bu ẹtẹ lu eto Ọlọrun fun igbala araye ti o ti nù, lati di i lọwọ ati lati pa a run. O bẹrẹ iṣẹ rẹ lori eniyan ninu Ọgba Edẹni o si ti n fi aiṣaarẹ lepa ipinnu rẹ lati pa ọkàn awọn eniyan run ni gbogbo ọna ti o ṣe e ṣe. O rú gbogbo idena ti a le gbero rẹ soke si awọn eniyan Ọlọrun lati akoko Mose titi fi di igba wiwá Jesu sinu ayé. Lẹyin naa o kọlu Olugbala wa ni ọjọ idanwo Rẹ o n fẹ ki Kristi gbọran si awọn imọran buburu rẹ ki O si tẹriba fun oun. Kristi bori rẹ nipa jijọwọ ifẹ Rẹ lọwọ fun ifẹ ti Baba Rẹ ni Ọrun. Satani ati awọn ogun rẹ nipasẹ akoso awọn ijọba ayé, ẹsìn eke, ati oriṣiriṣi ọgbọn ẹwẹ gbogbo ti sa ipa rẹ gẹgẹ bi ọmọ-alade agbara oju ọrun.

Psalmu yii mu ireti àaye ati idaniloju wá pe Kristi yoo jade bi aṣẹgun lori gbogbo agbara ẹ̀ṣẹ ati okunkun. Jehofa ti bura lati ri i pe a fi idi Messia mulẹ lori Itẹ́ Rẹ̀ lai fi awọn ọta ati idiwọ gbogbo pè. Nigba ti Baba bá dide lati mi ayé kijikiji, ki i ṣe pe a o ṣẹgun gbogbo idojukọ ati ọta nikan, ṣugbọn patapata ni a o tẹ ori wọn ba. Gbogbo idiwọ ni a o mu kuro pẹlu ọpa agbara ti yoo ti Sioni jade. Ijọba Kristi eyi ti Ijọ n ṣe oju fun nisisiyii ti ni idojukọ pupọ, ṣugbọn akoso Messia yoo jẹ́ patapata. "Awọn enia rẹ yio jẹ ọrẹ atinuwá" n tọkasi ifẹ awọn ayanfẹ Kristi lọpọlọpọ lati jẹ ọrẹ-ẹbọ atinuwa, wọn o yọ̀ọda ara wọn tifẹtifẹ fun isin Rẹ̀, ni ọjọ ijade-ogun Rẹ̀. "Ninu ẹwà iwa-mimọ́" n sọ nipa ọṣọ ati ifarahan ogun Kristi, iyin ati iwa pipé. Ni ọna ti Ẹmi, awọn eniyan Rẹ̀ jẹ orilẹ-ede ọba ati alufaa ti n ṣe iranṣẹ fun Ọba wọn, awọn ti a wọ̀ ni aṣọ oore-ọfẹ titayọ wọnni eyi ti aṣọ daradara awọn alufaa idile Aarọni duro fún. Messia ti n ṣiwaju awọn eniyan Rẹ̀ ni a ṣapẹẹrẹ Rẹ̀ bi ẹni ti o fi igba gbogbo wà ninu agbára ọdọ, ti ìrì owurọ oore-ọfẹ Ọlọrun ati Ẹmi Mimọ n tù lara ti o si n fun ni okun.

**Ipo Alufaa Rẹ̀**

Eto Oluwa fun Kristi jẹ alaileyipada, alailepaarọ̀, o si bori gbogbo idojukọ. "Iwọ li alufa titi lai nipa ẹsẹ Melkisedeki." Imọ akọkọ ti a kọkọ ni nipa Ọba Ododo yii wà ninu Gẹnẹsisi 14:18; O jẹ "Ọba Salẹmu" ati "alufa Ọlọrun Ọga-ogo." Oye alufaa rẹ ga ju ti Aarọni lọ, nitori Abrahamu san idamẹwaa fun un (Heberu 7). Lonii Kristi jẹ Olori Alufaa wa, O joko lori Itẹ́ Rẹ̀ gẹgẹ bi Onilaja. Ijọba Kristi ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun ki yoo jẹ kiki lori ẹniyan kọọkan lasan, ṣugbọn yoo jẹ lori gbogbo oyè ati ipo agbara laye ki a le tẹriba fun akoso Kristi nibikibi ti agbara ba gbé wà. Bi ẹnikẹni ba fẹ ṣe atako ti wọn si kọ̀ lati tẹriba, ọpa idajọ yoo "lù wọn." Kristi ki i ṣe Onilaja nikan, ṣugbọn Onidajọ ni pẹlu. Ihinrere Rẹ̀ ki i ṣe ọrọ aanu nikan; bi a ba kọ̀ ọ yoo di ofin idajọ. Ọpọlọpọ lonii n fẹ lati ronu nipa aanu Kristi nikan ṣugbọn aanu ti a kọ̀ silẹ a maa fa idajọ ododo ti i ṣe idakeji kan ṣoṣo ti o wà. Eredi ti a o fi fọ́ ori awọn olori ni orilẹ-ede pupọ ni pe wọn kọ̀ lati tuuba fun akoso ododo Rẹ̀. Gbogbo ipọnniloju ati agbara Aṣodisi-kristi ni a o tẹba, otitọ yoo si bori. Omi bibumu lati inu odo naa jẹ apẹẹrẹ itura lẹyin wahala ogun bi O ti n mu idajọ wá si iṣẹgun.

**Okuta Igun-ile**

Orin Dafidi 118:21-24 n sọ nipa "Okuta ti awọn ọ̀mọle kọ̀ silẹ li o di pataki igun ile." Idajọ eniyan ẹlẹṣẹ ninu ohun ti i ṣe ti Ọlọrun ko i ti fi igba kan dara rí. Eniyan ni ọna kan ti o dabi ẹni pe o dara, "ṣugbọn opin rẹ̀ li ọ̀na ikú" (Owe 14:12). Ipilẹ awọn Apọsteli ati awọǹ wolii ni pe "Jesu Kristi tikararẹ̀ jẹ pàtaki okuta igun ile" (Efesu 2:20). Peteru, bi o ti n waasu fun awọn olori, bi a ti kọ ọ silẹ ninu Iṣe Awọn Apọsteli 4:12 pe, "nitori kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là." Sibẹ awọn Ju rò pe awọn n gbeja ofin Mose, wọn fi I kọ́ sori agbelebu. Iṣẹ Oluwa ṣe iyanu ni oju wa, ni gbigbe Kristi ga, Ẹni ti a kan mọgi gẹgẹ bi ẹlẹtan, ti a si kọ̀ lọdọ awọn eniyan, lati jẹ́ Ọmọ-Alade ati Olugbala ati ori Ijọ Rẹ̀.

**Majẹmu Dafidi**

Orin Dafidi 132:11, ti n tọka si Majẹmu Ọlọrun pẹlu Dafidi lati gbe iru-ọmọ rẹ̀ kalẹ si ori itẹ́ Israẹli, ni a muṣẹ ninu Sọlomọni; ṣugbọn eto ijoba naa tayọ rekọja ti Sọlomọni nikan, nitori "Ọba Ogo," Olurapada ati Messia ti yoo wá lati gba awọn eniyan Rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn wà ninu eto naa. O tayọ eto irapada titi de akoko ti Kristi yoo jẹ́ Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa. Eyi ni yoo jẹ imuṣẹ 2 Samuẹli 7:16, "A o si fi idi itẹ rẹ mulẹ titi lai." A le jẹ alabapin ninu Ijọba naa nipa titẹriba fun Kristi ati gbigbọran si ifẹ ati Ọrọ Rẹ̀.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni awọn Keferi n binu si?
2 Ki ni Ẹni ti o joko ninu awọn ọrun yoo fi rẹrin?
3 Ta ni yoo lo ọpa irin?
4 Ki ni itumọ "Fi ẹnu kò Ọmọ na lẹnu?"
5 Ta ni Ọba ti a sọrọ rẹ̀ ninu Orin Dafidi 45:1?
6 Ta ni ayaba ti a sọrọ rẹ̀ ninu Orin Dafidi 45:9?
7 Ta ni Melkisedeki?
8 Ta ni okuta ti awọn ọmọle kọ̀ silẹ?
9 Njẹ a ha mu ileri ti a ṣe fun Dafidi pe, "Ninu iru-ọmọ inu rẹ li emi o gbé kalẹ si ori itẹ́ rẹ" ṣẹ ninu Sọlomọni? Ki ni ṣe?